# IROHIN IMỌLẸ

IMỌLẸ ORE AIYE, ṬENI GBOGBO LAWA

No. 701 FRIDAY, MAY 22, 1964 (2D)


## ARA OLUBADAN KO DA

IBADAN:— Ni kutukutu owurọ ana ọjọ ọjọ'Bọ ti iṣe ọjọ kọkanlelogun oṣu yi ni irohin kau wa lati Ibadan pe aisan nṣe Ọba Alaiyeluwa Isaac Babalọla Mabayẹjẹ Akinyẹle, Olubadan Ọba Ibadan, ti iṣe ọkan ninu awọn Minista ti ko ni iṣẹ pataki kanlati ṣe.

Oniwe irohin wa ni igboro ilu Ibadan fi ye wa pe niwaju Aafin Ọba Ibadan ni on duro si ti on si nkọ iwe yi. O fi ye wa pe ṣọṣọ ni Ile Olubadan kun fun ogunlọgọ awọn enia sarakisaraki, ati awọn ọrọkin ilu ti nwọn nlọ wo Ọba na lori akete aisan.

Ṣugbọn onirohin na ṣe alaye pe, diẹ ninu awọn enia na ri awọn alaṣẹ Ile Ọba na gba laye lati wọle, nwọn si da ọpọlọpọ awọn enia pada sẹhin, pẹlu gbolohun ọrọ pe, "Alagba, ẹ pada sẹhin ẹ ki o le ri Baba."

Ọkan ninu awọn alaṣẹ Ile Ọba na ṣe alaye pe, aisan agba ni o nṣe Ọba na, nitoripe ogbo ti de, ko si nkan miran ti o nyọ ọ lẹnu ju ogbo lọ.

O tun ṣe alaye pe ẹni ọdun mejilelọgọrin (82 years) ni Ọba Alaiyeluwa na, diẹ ninu awọn alejo ti nwọn wa lati Eko nikan ni nwọn ngba laye lati lọ ri Ọba na ati awọn Alufa oniwasu, nitoripe ọmọ Ijọ Aposteli ni Ọba na.

Ki Ọlọrun tete fun Ọba na ni alafia ki ọjọ rẹ o le di alẹ fun wa o.

# ILE IGBIMỌ APAPỌ IJỌBA FẸ ṢE IPADE PAJAWIRI

EKO:— Angbọ hunnu-hunnu nba lẹlẹ pe, akọwe Ile Igbimọ Asofin Apapọ Ijọba Nigeria ti fi iwe ipe ranṣẹ si gbogbo awọn ọmọ Ile Igbimọ na lati wa ṣe ipade pajawiri kan laipẹyi.



Dọkita M. I. Okpara
Alakoso Ijọba Ipinlẹ Ila—Orun

Gẹgẹ bi ohuu ti agbọ ninu ile iṣẹ wa ni alẹ ana, a gbọ pe ohun ti awọn ọmọ Ile Igbimọ na fẹ ṣe ipade le lori ni ẹjọ ti Ijọba Ipinlẹ Ila-Orun Naijiria pe Apapọ Ijọba lori abajade eto ikania

Ni ọjọ Aje ti iṣe ọjọ kejindinlogun osu yi ni Ijọba Ipinlẹ Ila Orun Naijiria pe Apapọ Ijọba Naijiria lẹjọ sinu Ile ẹjọ giga julọ ni orilẹ Ede yi.

Ninu ẹjọ ti Ijọba Ila Orun pe si ile ẹjọ na, Ijọba na ṣe alaye pe, Alhaji Abubakar Tafawa Balewa Alakoso Apapọ Ijọba Naijiria rekọja aṣẹ rẹ ti ofin iṣelu fun nipa gbigba ti o gba abayọri eto ikania eyiti o jade ni oṣu keji ọdun yi.

Ijọba na tun ṣe alaye ninu iwe ipẹjọ na pe ofin ko fun Abubakar laṣẹ lati gba abayọri eto ikania na.

Iwe ipẹjọ na tun ṣe alaye siwaju pe, Ọgọọrọ aṣiṣe ti ti ko ṣe fi oju foda, ti oju ti ri ti ẹnu ko gbọdọ ma sọ lọ wa ninu aṣiṣe eto ikania na.

Siwaju si, iwe ẹjọ na sọ pe, ko si ẹniti o fun Apapọ Igbimọ eto ikania na laṣẹ ki nwọn to gbe abayọri eto ikania na jade.

O tun sọ siwaju pe nwọn ko fun Igbimọ na ni aṣẹ lati ṣe iṣẹ wọn yekeyeke lọna ti o tọ ati ọna ti o yẹ, eyi lo si mu oke iṣoro ati idiwọ wa fun awọn enia na, ti o si tun fa ifasẹhin wa fun wọn.

Ni ipari, ipẹjọ na ṣe alaye pe, Apapọ Ijọba Naijiria ko ni aṣẹ kan labẹ ọrun yi lati gba abayọri eto ikania na nitori aṣiṣe ati aidọgba mọ ara wọn ti o wa ninu eto ikania na.

Irohin fi ye wa pe, Ijọba ti kọwe si Oloye J. M. Johnson, Minista Alamojuto eto iṣẹ pe ki o tete ma a bọ wale lati Ilẹ Amẹrika nibiti



Oloye J. M. Johnson
Minista Alamojuto Eto Iṣẹ

o gbe nṣe ipade lọwọ

Iwe ipe na ti de ọdọ Oloye J. M. Johnson yio si de si Eko laipẹyi. A gbọ wipe nitori ipade ti awọn ọmọ Ile Igbimọ Aṣofin na fẹ ṣe ni nwọn ṣe ranṣẹ si i pe ki o da ipade rẹ duro ki o tete ma a bọ.

Bakanna ni a gbọ wipe Alhaji Waziri Jalo, Alaga Ile Igbimọ Aṣofin Apapọ Ijọba Naijiria ti nṣe abẹwo awọn ilu yika orilẹ ede yi ti da irinajo rẹ na duro.

Alhaji Wasiri ti de Ipinlẹ Iwọ Orun Naijira, Ipinlẹ Ariwa ni on ati Alaga Ile Igbimọ awọn Agba Oṣelu Dọkita Orizu wa nisisiyi, Sug-

Wo Oju Ewe Kẹfa



Alhaji Abubakar
Alakoso Apapọ Ijọba

## ỌLỌLA ỌDẸLẸYẸ FADAHUNSI ṢE'BEWO

ỌYỌ:— Gbogbo awọn ara ilu bẹrẹsi yọ ṣẹṣẹ ti Ọba ati awọn Ijoye nki Ọlọla Ọdẹlẹyẹ Fadahunsi ni ma a wọlẹ nigbati Ọlọla na de si Ọyọ ni deede agogo mẹwa owurọ ana ọjọ ọjọ'Bọ ti iṣe ọjọ kọkandinlogun oṣu yi.

Irohin fi ye wa pe, Ọlọla Ọdẹlẹyẹ, Gomina Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria nṣe abẹwo awọn ilu kan si Ipinlẹ Iwọ Orun.

Nigbati Gomina na de Ọyọ lana, o ba awọn Igbimọ Ijoko awọn Alaṣẹ Ijọba Gusu Ọyọ sọrọ iwuri.

Ninu ọrọ rẹ, Ọlọla Ọdẹlẹyẹ dupẹ lọwọ awọn ọmọ Ile Igbimọ Ijọba Ibilẹ Gusu Ọyọ fun ayẹyẹ ariya ati ariyọ ti wọn ṣe fun on.

O wa mu ẹnu kan iṣẹ nla ribiribi ti awọn Igbimọ Ijọba Ibilẹ na ti nṣe lati ẹhin wa.

Ninu ọrọ rẹ, o kesi awọn ọmọ Ile Igbimọ na lati ma fi ifẹ ṣe iṣẹ wọn fun ilọsiwaju ati idagbasoke ilu Ọyọ ati fun anfani ati alafia gbogbo awọn enia ti o ngbe inu ilu na.

Lẹhinti o ba wọn sọrọ tan ni o wa lọ ṣe ibẹwo Ile ẹkọ giga St. Andrew College, Ọyọ. O si ki awọn olukọ ati awọn Tulẹ ti o wa ninu ile ẹkọ na.

Siwaju eyi ni ọlọla Ọdẹlẹyẹ tilọ fi oju kan Alaiyeluma, ọba Gbadegẹsin keji Alafin Ọba Ọyọ, awọn si jijọ fikunlukun.

Ṣugbọn nigbati o di alẹ ana, ni ọlọla na wa pe aṣẹ apejẹ ati apemu ranpẹ kan ni Ọyọ eyiti awọn Ọba, Ijoye Minisita, Ọlọla, awọn ọmọ ile igbimọ Alaṣẹ Ijọba

Wo Oju Ewe kẹfa

# IWA IBAJẸ TI O WA LARIN WA LONI"

Emi Ẹfufu Lẹlẹ nki gbogbo nyin wipe ẹku ọjọ mẹta Ṣe ara gbogbo nyin le dada? Bẹni mo ba ẹnyin ti ẹwa lode aiye yọ loni nitoripe ada ẹmi nyin si fun igba diẹ boya ẹ le ronu ki ẹ si pa iwa nyin da si rere. Bi emi Ẹfufu Lẹlẹ ti joko ti mo nba Ọlọrun ṣe apero iwa aiye.

Bẹni o ni ki mọleka amu nlwaiye ati eyi to munipada sọrun pe ki ogbe iwe Isipaya iwa awọn ọmọ enia aiye wa si ọdọ mi lati wo Ha! ha!! bi mo ti wo ni mo ri ti iwe na fẹrẹ kun tan

Iyanu ni awọn ọrọ isipaya nwọnni nitori iwa ọmọ enia aiye buru jai o ba ni lẹru pupọ ṣugbọn ko si ohun ibẹru kankan fun emi Ẹfufu Lẹlẹ Emi ẹni aiku ẹni aiyeraiye. Emi ti iku njuba ti osi nwari fun.

Bi mo ti joko ti mo nwo ni mo nri ti a pe orukọ awọn kan, Bi ati npe nwọn ninu awọn iwe yi ni mo ri awọn enia na ti nwọn fi aiye silẹ wa sọdọ Ọlọrun,

Ti ki ba ṣe pe emi Ẹfufu Lẹlẹ nṣe ẹni mimọ ni emi ki ba ri awọn enia wọnyi nitori nwọn ko si ninu ara ẹṣẹ mọ ohun ijinlẹ leyi fun awọn ọmọ enia ti mo ba da nu le lati ma sọ fun wọn bi emi ti ṣe wa lọrun lọhun ni

Papa gidi awọn Ogun Ọrun tilẹ sọ fun mi tabi ro mi lati ma ṣe itumọ bi Ọrun ti ri fun ẹnikan, Mo fi edidi di ọrọ isipaya yi.

Bi mo ti nfo bọ sinu aiye ni mo de Ẹkun ile ọmọ Oduduwa tabi adulawọ ti o wa ni agbegbe odo Ọya. Fifo ti mo nfo bọ ni mo wa ri ti gbogbo awọn oselu wọn nwa riri ti nwọn tilẹ fẹrọ ma kigbe pe awọn ko mọ bi aiye awọn yo ti ri.

Nitori pe awọn ti emi Ẹfufu Lẹlẹ fisi ipo ọla larin nwọn nti korọgbọn si ara wọn, niti pe a ka ara wọn. Emi Ẹfufu Lẹlẹ rẹrin wọn titi.

Mo wa bẹrẹ si sọ fun awọn enia na pe eyi ko to ibẹru rara. Ẹnikan ko le da ile yi ru rara ki emi to yan awọn aṣaju wọnyi mo ti ṣeto Ilẹ yi lati da ni ọla iwa rere.

Ẹniti o ba wipe on yo ba ilẹ na jẹ mo ṣe tan lati pe lọ si ibi ti awọn ara ṣaju lọ.

Ko si ẹniti o le dami lẹkun lati fi opin si igbesi aiye iru ẹni bẹ. Nitoripe ẹnikan ki jẹ awa de.

Kini ẹnyin Ọmọ npe ilẹ yi? Ilẹ ti mo da ninu ẹwa ogo ọla Tani ẹni na to le bajẹ tabi daru.

Mo fi iyẹ apa ẹmi Ẹfufu Lẹlẹ ṣe ẹlẹri mi pe ẹni to ba dawọ le iru ọrọ bẹ emi yio ran lọ si Ilu Ominihaha Elohimama.

Mo mọ pe orukọ yi yio ṣe ajeji si nyin nitori o jẹ orukọ aditu ọmọ enia. Bi mo ti nran iṣipaya mi si nyin bẹni mo ran awọn onisẹ mi lọ si ile igbimọ ti awọn aṣaju wọn yi nṣe ipade.

Emi Ẹfufu Lẹlẹ ko gbọdọ gbọ fin ọrọ ibajẹ kan rara larin awọn aṣaju nwọn yi. Nitori na Emi Ẹfufu Lẹlẹ nfi ọkan yin balẹ lori ọrọ yi.

Emi Ẹfufu Lẹlẹ nki gbogbo nyin lẹkan si i pe aiye nyin yio ba dada. Ẹ o si ma gbadun eso Ilẹ yi

Omi eso ilẹ yi yio ma kan si nyin lẹnu dada ọmọ nyin yio ma yọ ẹrẹkẹ ninu ajẹgbadun onjẹ Ile yi.

Ẹyin oṣiṣẹ Oniwe Imọlẹ mo fẹ sọ fun nyin ki ẹmura giri fun iṣẹ nyin. Laipẹ emi yio ran Manna lati ọrun si nyin lati jẹ.

Ẹ mọ pe ẹniti o ba jẹ onjẹ yi orungbẹ ki yio gbẹ mọ. Bẹni ebi ki yio pa mọ. Eyi nkọ ọmọ enia.

Emi Ẹfufu Lẹlẹ nrele o.
O digba kan na.

# O Ma Ku Ewu Ọjọ'bi Rẹ!

ITIRẸ:— Irọhin ko to afojuba ni ti inawo Ọjọ'bi Omidan Bọsẹde Shoyinka ati awọn Obi rẹ, Ọgbẹni ati Iyaafin J. O. Shoyinka Igbakeji Olotu Iwe IROHIN YORUBA ati Onitan Ajiran Ilu awọn Oku Abi-gege-ku-bi-ojo ṣe ninu ile wọn ni nọmba 1, Ishiba Street, Itirẹ ni ọjọ Abamẹta ti iṣe ọjọ kẹsan oṣu yi.

Oniwe Irohin wa Ejon'gboro fi ye wa pe, gbogbo ile lo kunṣọṣọ ti ẹsẹ ko si gba ero fun ogunlọgọ enia ti o wa ba wọn yọ ayọ ajọyọ Ọjọ'bi na ni ọjọ na.

Gbogbo awọn ọmọde l'ọkunrin ati l'obinrin ni Bọsẹde pe Ijọ fun ni adugbo pe ki nwọn wa ba on yọ ayọ ọjọ na, ki nwọn o si tun ba on jẹ onjẹ ti awọn obi ti pese silẹ.

Lẹsẹkẹsẹ ni awọn obi ọmọ na ti wọ aṣọ fun ọmọ wọn, ti nwọn si fun wọn laye lati ba Bọsẹde ṣe ayẹyẹ ọjọ na ninu ile wọn. Irohin fiye wa pe, ọmọ wẹwẹ ti Bọsẹde pe jọ ni ọjọ na le ni ọgọta.

Bi awọn ọmọ na ti pọ to, a jẹki ati amuti ni awọn ọmọ na fi onjẹ ati ọti Fanta ati Minrinda ṣe ni ọjọ na, awọn obi ti ọmọ wọn ko nile wa gba igo Fanta meji meji silẹ fun ọmọ wọn.

Lẹsẹkẹsẹ ti awọn ọmọde na jẹ ti nwọn mu tan ti onjẹ si tun ṣẹku nilẹ ni Iyaafin Shoyinka wa bẹrẹsi pin onjẹ na kakiri fun gbogbo awọn aladugbo ati awọn ti nkọja lọ, a fi awọn ti



BỌSẸDE SHOYINKA

ko kọja ni adugbo na ni ọjọ na ni ebi pa,

Awọn obi ọmọ na, na wabiwọsi owo, awọn aladugbo si sure fun wọn,

Awa Oniwe IROHIN IMỌLẸ ki omidan Bọsẹde ku ajọyọ ajọdun Ọjọbi rẹ Ọlọrun ko ni jẹki ododo rẹ ku ni kekere o.


BI O BA NI

Iwe—Titẹ

FUN

**Lilo nibi Iṣẹ rẹ tabi orişirişi iwe itufọ tabi ijade Oku**

ATI

**Iwe gbeyawo**

TETE KỌWESI ILE—IṢẸ—ẸRỌ ITẸWE

**Modupẹ Printing Press**

16, Bamgboṣe Street, P. O. Box 1495
Telephone: 21985, Lagos.

KETEKETE NI ẸRỌ ITẸWE WA NHAN
*OWO PỌKU NI A SI NGBA*

IROHIN KO TO AFOJUBA
*Dan wa we lẹẹkanṣoṣo ki o ri iyatọ*

# Awọn Ọlọpa Mu Ero Mẹkka

KANO:- Lẹnulọlọyi ni awọn ọlọpa mu ọkunrin kan Alhaji kan to ṣẹṣẹ nde lati Mẹkka. Gẹgẹbi ọkunrin na ti ṣe nsọkalẹ lati inu ọkọ ofurufu ni awọn ọlọpa mu ti nwọn gbe s nu mọto ti nwọn si walọ.

Awọn ọlọpa na fi ye onirohin wa pe idi rẹ ti nwọn fi mu ọkunrin na ni pe yio jẹ iranlọwọ fun nwọn lati ri ọkunrin kan ti nwọn ti nwa lati ọdun ti o kọja.

Awọn ọlọpa fi ye onirohin pe ọkunrin ti nwọn nwa na pe ti nwọn bari yoi jẹ ẹjọ fun ẹsun pe o l yi iwe ẹri iwa mọto ni Zaria.

Ọkunrin to ṣẹṣẹ de lati Mekka na nwọn si gba iduro awọn ọlọpa lu ki nwọn to tete fi silẹ.

## Dọkita Azikwe Lọsi Nsuka

Arẹ ilẹ Naijiria Ọlọla Dọkita Nnamdi Azikwe yio fi Eko silẹ ni ọjọ Abamẹta ti ṣe ọjọ kẹsan yi lọ si Nsuka.

Ni ọjọ kẹwa oṣu yi ni Adajọ agba ti ilẹ Naijiria yio jẹ adele fun Arẹ ilẹ Naijiria nibi isin kan ti yio wa ni ile Ọlọrun ti Christ Chucrh Cathedral fun isin ti awọn ọdọ ti gbogbo agbalye Oloye Adetokunbọh Ademọla ti yio ka ọrọ ti Ọba ilu Gẹẹsi fi ranṣẹ si awọn ọdọ ilẹ Naijiria.

Isin ọjọ na yio bẹrẹ ni agogo mọkanla owurọ. Iru isin na yio si kakiri ilẹ Naijiria ni ile Ọlọrun jakej do ilẹ Naijiria

## YẸ IRAWỌ RẸ WO

AQUARIUS (Jan 20-Feb 18) Sa joko jẹjẹ ki o si ro gbogbo ohun ti o ti nṣe latẹhin wa maṣa fi agbara ṣe nkan ti ko si.

PISCES (Feb 19-March 20) Arẹ ara yio wa fun ọ nigbati o ba di ọsan, nitori na ki o tete yanju awọn ọrọ to ba ṣe pataki ki akoko na to de ṣugbọn iṣẹ rẹ yio ma lọ deede.

ARIES (March 21-April 19) Ọjọ oni yio ṣoro fun ọ ati wahala lati ọdọ awọn ẹbi rẹ gbogbo iwọnyi ko di iṣẹ rẹ lọwọ fi ẹnu rẹ ninu ki o ba le bo aṣiri ara rẹ diẹ.

TAURUS (April 20-May 20) Awọn ọrọ to ba ṣe pataki nikan ni ki o mojuto loni ki o si fi iyoku silẹ, nitoripe ara rẹ ko fẹ wahala pupọ ọjọ ire sunmọ tosi tan fun ọ.

GEMINI (May 21-June 21) Amọdi nfẹ ṣe ọ, ṣugbọn ki di iṣẹ rẹ lọwọ ipade ẹgbẹ ti iwọ yio ba wọn ṣe, ire yio ti ibẹ yọ jade wa fun ọ.

CANCER (June 22-July 22) Iṣẹ ati idunnu yio pọ fun ọ loni awọn o si bere ọrọ pataki lọwọ rẹ nipa iṣẹ rẹ Obinrin kan yio ba ọ ṣere irẹpọ iwọ pẹlu rẹ yio fi idi mulẹ.

LEO (July 23-Aug 22) Oyẹ ki o lọ ba awọn enia pataki sọrọ ni toripe ayonusi ṣẹ npọ, awọn ni yio jẹ igi lẹhin Ọgba fun ọ.

VIRGO (Aug 23-Setp 22) Ina ari siki rẹ ntan imọlẹ atojubọ rẹ nipa ohun kan ti o fẹ ṣe dara Oluwa kan yio ba ọ sere gele ṣugbọn awọn ọrẹ rẹ ki ni se ohun ti o wu ọ tabi to dunmọ ọ ninu.

LIBRA (Sept 23-Oct 23) Irọlẹ ọjọ oni yio milnijọ fun ọ ati fun alafia rẹ awọn enia nlanla yio fun ọ ni imọran iṣẹ rẹ yio pọ si rin faaji lọ si ode kabọ.

SCOPIO (Oct 24-Nov 22) Ire mbẹ fun ọ loni dara-dara bi o ba le mu ẹsẹ rẹ duro giri giri Iwọ yio tilẹ ri ire ti iwọ ko lero.

SAGITTARIUS (Nov 23-Dec 21) Bi o ba ni kotu loni ẹjọ na yio gbe daadaa o si tun dara bi o ba lọ ri awọn ijimi enia, maṣe fi agbara fa ọrọ bi nwọn ba ti fi ọrọ na si ni ki o gba a.

CAPRICORN (Dec 22-Jan 19) Iwọ yio ṣe orire ninu ọrọ pataki kan ṣọra maṣe aṣerege maṣe ṣe ṣẹgalegale kan, ire ni igbẹhin rẹ yio jẹ fun ọ.


# EGBOGI JẸDIJẸDI

BERE EGBOGI



## "CYCLOVN"

Aworan oke yi fi han gbangba ibiti Jẹdijẹdi rẹ gbe wa lara rẹ si nyọ ọ lẹnu nigbagbogbo. Ihẹ ni a npe ni "omusu tabi Iho idi enia ibiti a ma ngbe ṣe igbọnsẹ. Arun Jẹdijẹdi jẹ ọkan ninu amodi ti o buru ni pataki fun Ọkunrin ti o si lagbara pupọ lati ṣe iwosan rẹ patapata.

Ọpọlọpọ egbogi ni nwọn nta kakiri lode nisiyi ti wọn a ma po owo wọn fun iwosan rẹ ṣugbọn boya la leri mẹwa ninu ọgọrun ti o le ṣe iwosan arun yi daradara, Awọn ẹlomiran lero wipe bọya bi wọn ba lọ si ile Dokita lati lọ ke eyiti o ba nyọ jade lati omusu ku ni pa bẹ awọn o bọ lọwọ rẹ patapata.

Ṣugbọn awa ko ro bẹ rara. Lẹhin ọdun diẹ iyọnu rẹ yio si tun bẹrẹ bakana. Orişirişi Jẹdijẹdi ni o wa ekini ti o bẹrẹ nipa aiko mẹ ṣe igbọnsẹ dede tabi lojojumọ, ẹlomiran nipa ijoko ni ojukanna pẹlu lojoujmọ tabi gigun kẹkẹ ologere (Basikulu, pupọ ẹlomiran ẹwẹ nipa jijẹ Ṣuga tabi oniruru ohun adidun pupọju nigbakugba. Jẹdijẹdi orişirişi ni o wa, ewo ni tirẹ? Bi o nyọ ade inu omusu, tabi ti o ba nmu ẹjẹ wa lẹhin igbọnse, tabi ti o ba nyọ ti o ba ṣe igbọnṣẹ tan ni, tabi ti nrin ọ ninu omusu ni eyikeyi ti o ba ra bere egboogi "CYCLOVEN" ti awọn Oyinbo Jamani ṣẹṣẹ wa ldi rẹ kio si panwo orişi mẹta ni o daju wipe iwọ yio bọ lọwọ Jẹdijedi patapata alafia yio de si ekeji rẹ ko si ninu gbogbo egbogi atata igboro Naijiria jakejado. Bere rẹ ni:

Waterloo Medicine Stores
8, Palmchurch Street, Lagos
Phone: 22878 Nigeria. (Oja Ita Faji)
ADEDUN CHEMIST
14. Wakeman Street Lagos
NIGERIAN MEDICINE STORE
Tinubu Square Lagos.

# Congreves Remedy

(FUN OBINRIN)

Ojulowo egbogi titun fun gbogbo awọn Obinrin boba ni iyọnu tabi amodi Inu rirun nigbakugba tabi ni ẹkọọkan ẹhin-didun, Ibadi-wiwo tabi sisan ẹjẹduda ara tabi aikoto ẹjẹ lara Inu gbigbona nigbakugba Igba — aiya riru ọmu riro, didun ara atinu wa ni o ma nfa oyi - oju Ilaogun ata ẹsẹ ara sisọn, ẹfọri tabi pẹlu iba ati otutu Egbogi yi dara pupọ julọ fun itọju gbogbo O b i n r i n gẹgẹbi Ajo fun ilera ati orişirişi amodi miran ti o ma nyọ wọn lẹnu ni inu igbakugba pẹlu.

(OLOMI IGO NLA NI)

BERE EGBOGI ATI JỌ TI WỌN NPE NI:-

## Ammoniated Quinine Tincture

Nigba lailai ki awọn Orişirişi rọbirọbi egbogi ti wọn ko wa nisisiyi to de awọn agbalagba aiye atijọ mọ daju wipe kosi ohun ti a le fi Iwe egbogi yi bi otutu ikọ iba, orẹrẹ lukuluku onigbameji tabi a i p e r i nyọ enia lẹnu yala Ọmọde tabi agbalagba ni yio ṣe iwosan rẹ bi danga ni bi oba ti ta diẹ sinu omi ti o lọwọrọ ki o si gbemu bere egbogi ti o daju fun itọju eti riro tabi didun, ati Akokoro, egbogi ti o ma nfọ apo-ile-itọ tabi se iwosan iyọnu apo-ile-itọ egbogi oju didun tabi ti ọna-ọfun didun, ati orişirişi omiran pẹlu wọn mbẹ ni ṣọbu awọn :—

Waterloo Medicine Stores,
8, PalmChurch Street, Lagos.
Phone:- 2287 Nigeria, (Ọja Ita Faji)

